# OJUṢE ONIGBAGBỌ́ LAAARIN ILÚ

## Romu 13:1-14; 14:1-23; 15:1-33

## ẸKỌ 388 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Njẹ nitorina, ki awa ki o mã lepa ohun ti iṣe ti alafia, ati ohun ti awa o fi gbe ara wa ró" (Romu 14:19).**

**I Itẹriba fun Awọn Onidajọ**

1 Eto ijọba ilu jẹ gẹgẹ bi ilana Ọlọrun a si ni lati tẹriba fun aṣẹ rẹ, Romu 13:1, 2; Titu 3:1; 1 Peteru 2:13, 14.

2 Agbọdọ tẹriba fun awọn alaṣẹ ilu nitori awọn ni a fi itọju ofin ati ilu le lọwọ, Romu 13:3-7.

**II Iṣẹ Onigbagbọ́**

1 Awọn Onigbagbọ́ ni lati fẹran ọmọ-nikeji wọn, Romu 13:8-10; Galatia 5:14; Jakọbu 2:8

2 Jẹ ki imọlẹ Ihinrere tan to bẹẹ gẹ ti awọn ẹlẹṣẹ yoo le bọ ara iṣẹ okunkun silẹ ki wọn si gbé Jesu Kristi Oluwa wọ̀, Romu 13:11-14; 1 Kọrinti 15:34; Efesu 5:14; 1 Tẹssalonika 5:5, 6.

**III Idajọ Aitọ́**

1 Onigbagbọ́ kò gbọdọ dá ẹnikeji rẹ lẹjọ nipa ounjẹ tabi ikiyesi awọn ọjọ, Romu 14:1-6; 1 Timoteu 4:4; Kolosse 2:16.

2 Ẹ jẹ́ oninuure si awọn ti o ṣe alailera: gbogbo wa ni yoo duro niwaju itẹ idajọ Kristi, Romu 14:7-16, 20, 21; 15:1-3; 1 Kọrinti 8:9-13; 2 Kọrinti 5:10.

3 Ijọba Ọlọrun ki i ṣe ti wiwá awọn nnkan ode-ara. Ẹ jẹ ki a maa ṣe ohun gbogbo ninu ẹmi igbagbọ́ ati ni gbigbe ẹni keji wa ró, Romu 14:17-23, Matteu 15:11.

**IV Igbala fun Ju ati Keferi**

1 Iwe Mimọ́ fi hàn pe Jesu Kristi ki i ṣe ti awọn akọla nikan ṣugbọn o wá fun igbala awọn Keferi pẹlu, Romu 15:8-12; Orin Dafidi 18:49; Isaiah 11:10; Johannu 10:16

2 Ọlọrun ireti le fi gbogbo ayọ oun alaafia kun ọkan yin ni gbigbagbọ, Romu 15:13.

**V Akotan Eto Paulu**

1 Paulu sọ nipa iṣẹ ami ati iṣẹ-iyanu ti Ọlọrun tipasẹ rẹ ṣe ati ti ipinnu rẹ lati rin irin-ajo lọ si Spania. O sọ pẹlu nipa irin ajo rẹ lọ si Jerusalẹmu pẹlu owó ti a dá fun awọn eniyan mimọ́ ti wọn jẹ talaka, Romu 15:15-33.

### ALAYE

**Ijọba Ilu**

Ijọba ilu jẹ ilana Ọlọrun Ẹni ti i ṣe Alakoso ti o ga ju lọ ni gbogbo agbaye. Otitọ ni pe Oun a maa fi aṣẹ fun ẹnikẹni ti o ba wu U, "Nitoriti igbeleke kò ti ìla-õrùn wá, tabi ni ìwọ-õrùn, bẽni kì iṣe lati gusu wá. Ṣugbọn Ọlọrun li onidajọ: o sọ ọkan kalẹ, o gbé ẹlomiran leke" (Orin Dafidi 75:6, 7). Nigba pupọ ni alakoso ilu ki i ṣe ẹni iwa-bi-Ọlọrun, sibẹ lati ọdọ Ọlọrun ni akoso ijọba ti n wá; nitori lai si rẹ ki yoo si akojọpọ eniyan, ki yoo si aabo ni ilu. Gbogbo nnkan yoo si di rudurudu.

Ọlọrun fi hàn fun wa pe Oun fẹ eto ati iṣedeedee nigba ti O fi oorun, oṣupa ati irawọ si àye wọn loju ọrun ti olukuluku wọn si n tọ ipasẹ ọna ti rẹ loju ọrun lai tase lati ọdun dé ọdun.

Pupọ orilẹ-ede ni o ni ohun ti a n pe ni eto iṣakoso eyi ti i ṣe ilana ti a fi n ṣe akoso ilu. Eto iṣakoso yii jẹ igbekalẹ ti o yẹ ki o jẹ fun anfaani awọn ara ilu. Alakoso, i baa jẹ ẹni ti a fi ìbo yàn, tabi ẹni ti a yàn lai si ibo tabi ẹni ti o de ipo yii nipa ìbí, ti ṣeleri lati ṣakoso awọn eniyan nipa eto iṣakoso naa. Ati gẹgẹ bi Ọlọrun ti jẹ Olupilẹṣẹ ofin ati eto, alaṣẹ naa ti o ba n ṣe akoso ilu gẹgẹ bi eto iṣakoso ilu naa, Ọlọrun ni o yàn án.

**Igbọran si Ofin**

Paulu sọ eredi meji pataki ti a fi ni lati tẹriba fun awọn alaṣẹ ti o wa ni ipo giga. Ekinni ni lati bọ́ kuro ninu ijiya ti aigbọran n mu wá, ekeji ni lati ni ẹri-ọkàn rere. Eredi meji pataki yii ki yoo jẹ

ki a jẹ arufin, yoo si mu wa tẹriba fun Ofin. Igbọran a maa mu ibukun wá, ṣugbọn aigbọran a maa mu ègún wá.

**Sisan Owo-ode Ṣe Deedee pẹlu Ofin**

Ijọba ilu jẹ ilana Ọlọrun. Owo gọbọi ni a si n ná lori pipese aabo ati ipamọ fun awọn ara ilu. O si tọna pe ki awọn ti a n titori rẹ̀ ṣe inawo yii ṣe iranlọwọ nipa sisan owo naa. Owo-ode ti o ba ṣe deedee pẹlu Ofin tọna fun wa lati san. Ni ọna keji, ofin Ọlọrun ko fi ìdí owo-ode ti o ga ju mulẹ, iru eyi ti awọn alakoso ti ko bikita n bu fun awọn eniyan lati san. Ṣugbọn nitori ẹri ọkàn, awọn ọmọ Ọlọrun gbọdọ tẹriba fun awọn ofin ilu. "Nitorina san ohun ti o tọ fun ẹni gbogbo: owo-ode fun ẹniti owo-ode iṣe tirẹ; owo-bode fun ẹniti owo-bode iṣe tirẹ̀; ẹ̀ru fun ẹniti ẹ̀ru iṣe tirẹ̀; ọlá fun ẹniti ọla iṣe tirẹ̀."

A gbọdọ fi ọla fun awọn alaṣẹ nitori ipo wọn. Bi alaṣẹ naa tilẹ jẹ oniwakiwa eniyan, bu ọla fun oye rẹ̀ ati oun paapaa nitori ipo rẹ̀. Ma ṣe huwa ti kò tọ́ si ẹnikẹni.

**Ipilẹ Ofin Ọlọrun**

Paulu Apọsteli ti n fi ojuṣe wa, ibọwọ ti a ni lati ni ati igbọran wa si awọn onidajọ wa hàn wa. Nisisiyii, gẹgẹ bi Onigbagbọ́, o n fi iṣẹ wa si ọmọnikeji wa hàn wa. Ifẹ ni ipilẹṣẹ ofin Ọõrun. "Ẹ máṣe jẹ ẹnikẹni ni igbese ohun kan, bikoṣepe ki a fẹran ọmọnikeji ẹni." A kan an nipa fun wa lati tẹriba fun ofin ilẹ wa nitori ẹri-ọkàn wa; ṣugbọn a fi okun ifẹ so wa pọ pẹlu ara wa. "Ifẹ ki iṣe ohun buburu si ọmọnikeji rẹ̀: nitorina ifẹ li akoja ofin." Igbagbọ́ n so wa pọ mọ Ọrun; ireti ki i si dojuti ni; ṣugbọn ifẹ ti o kun ọkan wa lati ọdọ Ẹmi Mimọ́ wa ni o tobi ju gbogbo wọn lọ.

**Ijiyan Laaarin Ju ati Keferi**

O ṣe e ṣe ki ede-aiyede ki o wa laaarin awọn Ju ati awọn Keferi Onigbagbọ́ ni ilẹ Romu. Ifẹ Ọlọrun bukù laaarin wọn. Ohun ti o mu ede-aiyede naa wa ni nipa ounjẹ ati awọn ọjọ.

Diẹ ninu awọn Ju ti o ni iyipada ọkàn gba pe wọn gbọdọ pa Ofin Mose mọ́. Wọn ka awọn ounjẹ kan si alaimọ ti wọn ko gbọdọ jẹ, a ti pe a gbọdọ bu ọla fun awọn ọjọ ayẹyẹ pataki kan. Keferi ti o di Onigbagbọ gba pe isin Kristi ko fi iru ajaga bẹẹ bọ oun lọrùn. Awọn mejeeji, Ju ati Keferi le jẹ oloootọ ninu ironu wọn; bi wọn si ti jẹ oloootọ ati ẹni diduro ṣinṣin ti wọn si n gbe pẹlu ibẹru Ọlọrun, wọn le jẹ ajumọ-jogun iye ainipẹkun. A sọ nipa ẹni kọọkan wọn bayi pe: "Loju oluwarẹ̀ li o duro, tabi ti o ṣubu."

Jesu Oluwa mu un dá Paulu loju pe ko si ohun kan ti o ṣaimọ fun ara rẹ̀. Ṣugbọn bi arakunrin kan ba ṣe alailagbara ti o si ka ohun kan si aimọ́, a gbọdọ yẹ́ igbagbọ́ rẹ̀ si, ki a má si ṣe pa igbagbọ ẹni ti Kristi kú fun run. Jẹ ki ọkan rẹ̀ ki o ṣe iyebiye ni oju rẹ, ki o má si ṣe fi ohun idugbolu si ọna rẹ̀. Eyi fi hàn pe nipa iwa ailọgbọn wa, a le pa ẹmi kan run. Wo bi o ti niye lori to ki awọn Onigbagbọ́ ki o maa rin pẹlu ọgbọ́n ati ifẹ niwaju Ọlọrun! "Nitori ounjẹ máṣe bi iṣẹ Ọlọrun ṣubu." A le fi eyi kun un pe: Nitori ede aiyede keekeekee ma ṣe jẹ ki arakunrin rẹ kọsẹ ki o si ṣubu.

Ẹni kan le gbagbọ́ pe gbogbo ohun ti Ọlọrun dá, rere ni o si njẹ ẹ, o si n buyin fun Ọlọrun. Ẹni keji le maa yẹra fun awọn oriṣi ounjẹ kan. Oun kò jẹ ẹ́, o si n fi ọpẹ fun Ọlọrun. Ọlọrun tẹwọ gba mejeeji, wọn si ni lati fara da a fun ara wọn. "Nitori ijọba Ọlọrun ki iṣe jijẹ ati mimu, bikoṣe ododo, ati alafia, ati ayọ̀ ninu Ẹmi Mimọ" Ki i ṣe nipa awọn nnkan ode ara ati awọn ohun-ini aye yii, ṣugbọn nipa idariji ẹ̀ṣẹ, igbesi-ayé mimọ́ ati ọkàn funfun. A maa n ni alaafia ọkan nigba ti a ba ri aanu Ọlọrun gbà ti a si tan ifẹ Ọlọrun ká inu ọkàn wa.

Ẹni kan wi bayii pe: "Dajudaju Ọrun gan an ni eyi; ododo lai si ẹ̀ṣẹ, alaafia lai si iyọlẹnu, ayọ̀ lai si ibẹru ati idaamu."

**Awọn Ọjọ Ajọ**

Awọn Keferi ti o di Onigbagbọ ko ka awọn ọjọ ase awọn Ju bi Pẹntikọsti ati oṣu titun gẹgẹ bi apa kan Ihinrere Jesu Kristi bi ko ṣe bi ilana isin awọn Ju labẹ Ofin. Nitori ti awọn Ju ti n pa awọn ọjọ ase wọnyii mọ́ fun igba pipẹ, wọn kà wọn si ọjọ ọlọwọ, nitori naa wọn ṣi teramọ ati maa pa wọn mọ́. "Ẹniti o ba nkiyesi ọjọ, o nkiyesi i fun Oluwa; ẹniti kò ba si kiyesi ọjọ, fun Oluwa ni kò kiyesi i." "Ẽṣe ti iwọ fi nda arakunrin rẹ lẹjọ? tabi esitiṣe ti iwọ fi nkẹgan arakunrin rẹ̀? gbogbo wa ni yio sá duro niwaju itẹ́ idajọ Kristi."

Igba pupọ ni ibeere jade nigba aye awọn Onigbagbọ akọkọ nipa pipa Ofin Mose mọ́. Awọn Apọsteli pejọ pọ lati yanju ibeere yii, a si le ri ipinnu wọn ninu Iṣe Awọn Apọsteli ori kẹẹdogun. Paulu ṣe alaye lori beere yii nibi pupọ ninu Episteli rẹ̀. Pupọ ẹlẹkọ eke ni o wà lọjọ oni ti wọn n fẹ mu wa wá sabẹ ide Ofin Mose ni pataki, nipa pipa Ọjọ Isinmi mọ́. Ṣugbọn Bibeli sọ bayii pe, "Nitorina ẹ máṣe jẹki ẹnikẹni mã ṣe idajọ nyin niti jijẹ, tabi niti mimu, tabi ni ti ọjọ ase, tabi oṣù titun, tabi ọjọ isinmi" (Kolosse 2:16).

Jesu jinde ni "ọjọ ikini ọsẹ"; o jẹ ọjọ ti Jesu fi ara Rẹ̀ han awọn Apọsteli Rẹ̀ ni ọpọlọpọ igba lẹyin ajinde Rẹ̀; o jẹ ọjọ ti agbara Ẹmi mimọ́ sọkalẹ (Iṣe Awọn Apọsteli ori keji), ni akoko ti a dá Ijọ Kristi silẹ. O jẹ ọjọ ti awọn ọmọ-ẹyin pade lati bu akara ni iranti Ounjẹ Alẹ Oluwa, ti wọn si mú ọrẹ wọn wá fun Oluwa. Nitori idi wọnyii a ka Ọjọ Ọsẹ gẹgẹ bi Ọjọ Oluwa, a si ya a sọtọ fun ọjọ isin.

### Ẹri-ọkàn Wa

"Alabukun-fun ni oluwarẹ̀ naa ti ko da ara rẹ̀ lẹbi ninu ohun ti o yà." Ẹni ti o le ni alaafia ọkan ni oluwarẹ̀ naa ti o n tẹle itọni ẹri-ọkàn rẹ̀ niwọn bi ihuwasi rẹ̀ kò ti lodi si Ofin. Kò le si alaafia fun oluwarẹ ti o n ṣe awọn ohun wọnni ninu eyi ti ti ẹri-ọkàn rẹ̀ n da a lẹbi tabi ti o fi i sùn. "Ohunkohun ti kò ti inu igbagbọ́ wa, ẹṣẹ ni."

### Owurọ Ọjọ Titun

"Oru bukọja tan, ilẹ si fẹrẹ mọ́: nitorina ẹ jẹ ki a bọ́ ara iṣẹ òkunkun silẹ, ki a si gbe ihamọra imọlẹ wọ̀." Awa n sún mọ́ owurọ igba titun; Jesu duro ni ẹnu-ọna, O si n kankun. Okunkun yoo ká kuro lai pẹ. Akoko iṣẹ wa fun Jesu yoo kọja lai pẹ. Ọpọ ọkàn ti n ṣegbe yoo bẹrẹ si i kigbe pe "ikore ti kọja, ẹ̀run ti pari, a kò si gba wa la!" (Jeremiah 8:20). Ẹ jẹ ki a ṣiṣẹ nigba ti a ba n pe e ni oni, nitori oru n bọ nigba ti ẹni kan ki yoo le ṣe iṣẹ. "Ẹ mã rù ẹrù ọmọnikẹji nyin, ki ẹ si fi bẹ̀ mu ofin Kristi ṣẹ."

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti a fi n san owo-ode?
2. Ọna wo ni Peteru gba lati ri owo-ode ti o san fun ara rẹ̀ ati Jesu pẹlu?
3. Sọ eredi meji ti a fi ni lati gbọran si awọn ofin ilẹ wa.
4. Ki ni ija ti o wà laaarin awọn Ju ati awọn Keferi ti o wà ni ilẹ Romu?
5. Ki ni wa ninu Ijọba Ọlọrun?
6. Ki ni Paulu sọ ninu Episteli rẹ̀ yii nipa akoko?
7. Bawo ni Onigbagbọ́ ṣe ni lati bá ara wọn lò?
8. Iha wo ni Paulu kọ si ounjẹ jijẹ bi o ba jẹ ikọsẹ fun arakunrin rẹ̀?